# EKO AKETE ROYAL EDITION.

PRINCE OF WALES' NUMBER.

**April 11, 1925.**

16 APR 1925 LAGOS



*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Offices:* 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|
| Ọdun kan 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor.*

## GBOHUN-GBOHUN.

——:o:——

### EYI TI JẸ O?

Ihin kan ni lati Ebute Mẹta pe nigbati Dokita Ladapọ Oluwọle ti fi iwe owo (*Cheque*) sanwo bi lile ni pọun meji fun Ọgbẹni J. Mọṣalewa Thomas aṣoju kekere ti Ile-ọ̀wọ̀ *Lagos Stores* ni Ebute Mẹta, ni lọlọyi ti o si sá Ọgbẹni na ni'jà lati fi otitẹ onikọbọ meji si iwe ẹri (*Receipt*) isanwo ti Ile-ọ̀wọ̀ Oyinbo rẹ (*Printed Receipt Form of the Firm of Lagos Stores Ltd*) ti o fi ṣọwọ si Dokita na, bẹni ọrọ di ti Kotu Ebute Mẹta, a si sọ pe Adajọ ibẹ fà ıkọ lati bu pọun mẹwa ti ofin da ni seria fun irufẹ "ẹṣẹ" bẹ ni sisan sinu Apo Ọba, fun Ọgbẹni Thomas ni sisan. Ẹjọ ṣi sun sibi, lẹhin igbati Adajọ na ba ti da seria ẹjọ yi tan, a le sọrọ gbolohun meji, tabi mẹta si i.

### ỌGBẸNI SHYNGLE ỌLỌLA BU RAMU-RAMU, GBOGBO IGBO GBOJIKAN.

Ni Arọ *Tuesday* ọsẹ yi ni Ganran ni Ọgbẹni Shyngle Ọlọla sọ iwe ẹjọ ti Adajọ Kotu Ọlọpa fi ṣọwọ si Adajọ Agba fun yiyẹwo nipa bi o ti dajọ Dokita Sẹsi Kapo ati Albert Taiwo si, d'oku: Kotu Ganran si tun pa l ṣẹ pe ki Ọgbẹni Adajọ Kotu Ọlọpa yi tun wa kọwe ẹjọ na miran, ki o o si fi idi abajọ ti o ṣe dajọ bẹ ti i.

———————

### MEMORABLE EVENTS.

Foundation Stone of Christ Church, Lagos, laid by His Excellency the Governor Sir John Hawley Glover March 29 1867.

Foundation Stone of Christ Church Pro-Cathedral Lagos, laid by His Royal Highness the Prince of Wales, K.G. April 15, 1925.

### FROM DENIGA'S "NOTES ON LAGOS STREETS."

(*Copyright*)

**Historical Notes of the Principal Streets in town through which His Royal Highness accompanied by His Excellency the Governor, will drive on Tuesday the 14th instant at 10 a.m.**

#### MARINA (ẸHINGBẸTI).

This is named thus, owing to its being the chief place in which all refuse and dirt is generally deposited in the early days of Lagos.

#### TINUBU SQUARE.

This important Square, on which stands the Court House, is named after a lady by the name of Efunroye Tinubu an Ẹgba, that may be said to have been the Iyaloja of Lagos in years gone by; she came over from Abẹokuta to this country through Badagry and carried on a most flourishing trade in Tobacco, etc. and was possessed of many slaves. She owned the present site of the Lagos Police Force, which it is said, she gave to the late Captain J. P. L. Davies in satisfaction of a debt. She left Lagos for Abẹokuta on Tuesday 15th April, 1856, never to return.

#### BROAD STREET.

This is a principal thoroughfare. It extends from the Race Course the Fields, to Pearse Square, Oke Olowogbowo a distance of about 1½ miles or 7721 feet or 11700 links.

#### VICTORIA ROAD.

This is named after Queen Victoria, popularly known as Victoria the Good on account of her peaceful reign; she was born in 1819 Ascended the Throne 1837; Joined the great majority January 21, 1901.

#### BALOGUN STREET OR SQUARE.

This spot is named after a man Ajeniya by name whose official title is the Balogun of Lagos: he began to flourish during King Akitoye's time and took a very active part in all the wars of that time.

———————

### TANI FẸ KA NI, B'IKOṢE ỌLỌRUN.

[ Lati ọwọ AKIRIMANU. ]

Si Oni'we irohin "*Eko Akete.*"

Mo juba o,

Nigbati a gbo ti odemọkunrin wa kan to lo si Saro lati ko iwe ti owo si tun lọwo rẹ ti o si damọran lati ṣe iṣẹ Alufa tun Ijọ kan, ti o si kọ iwe si won fun iranwo inu wa dun pupo fun imọran rere ti o jade ni ọkan ọmọde yi, ṣugbọn obisa ẹdun ta

wa nibẹ ni pẹ awọn Ijo yi mura lati kọ iwe si pada pe awọn ko ni owo ni l·, ni oju ti awa a rope bi ọmọde yi baję ọkan ninu awọn bi ęni bi ęni wara-were ni mo ro pe awọn o gba imẹran na, ṣugbọn a dupę pe Ọ·bęni w· J H. Doherty ti gba ęru na kanri pe on yio r·n·mọ na lowọ ati pe bi o ba pada de ki o wa lọ si ilu Iya on lati ma kọ wọn ni ękọ ile iwe g ga nibę, ki Ọlọrun tun bo sun ęmi Ọgbęni wa yi siwaju Ashley Oluwa na to mu o lọ yio ran ọ lọwọ (*let not your heart be trouble trust in God and do the right.*)

Ni ọsu d ę sęhin ni a fi ęmi kan awọn Onigbagbọ titun ti arin wa ni igboro Eko yi (*Faith Tabernacle*) awọn wọnyi ni a sọ pe ogun lilo si aisan jẹ ohun eri lo ju won ṣugbọn ni koi pẹ yi ni a gbọ pe olori awọn Ol pa (*Suptd: of Police*) ranṣẹ pe ọdẹ mọkunrin kan akọwe Ọgbẹni olowo kan lati bere ohun ti o mọ nipa iku obinrin kan ni ita "X" ni cṣu kẹrin to kọja.

Ohun ti a gbọ ni pe obinrin na bi ọmọ titun, awọn Onigbagbọ wọnyi ko si fun ni aye lati mọ ara pẹlu omigbigbona bi o ṣe omi tutu, agbare-gbabọ ara tutu ni obinrin yi pẹlu alejo titun yi ba di ero ọrun apapandodo.

A o tun sọ si ọrọ na nijọmiran.

Emi ni tinyin nitotọ,
AKIRIMANU.

---

**Wales, H. R. H. the Prince of. Edward Albert Christian George Andrew Patrick David**, born June 23, 1894 Received naval training at Osborne and Dartmouth; coxswain to a winning pair in the Dartmouth Regatta, 1910 Invested as Prince of Wales at Carnarvon, 1911. Midshipman on Hindustan, whose commander said; "The Prince has, throughout the whole period of his training, been an extremely hard worker, and has struck at all there about him, high and low, as what we call a live thing.'" K.G., June 1911. Stayed some months in Paris, acquainting himself with France and the language in, 1912. Received the Legion of Honour from the President (July, 1921), and the Croix de Guerre (October 1915). Promoted lieutenant on eve of taking a tour in Germany, March, 1913. Went through an undergraduate course at Magdalen College, Oxford. Performed first public duty by laying foundation stone of S. Anselm's Church Kennington, in June, 1914. Went to the front in Nov., 1914, attached to Sir J. French's Staff. Served with zeal and ability, and was the bearer of historic despatch from Sir J French respecting the Battle of Neuve Chapelle Celebrated quietly his 21st Birthday, June, 1915. The Order of the Annunziata was given him by the King of Italy in July. Arrived in Egypt in March, 1916, on appointment as Staff-captain on the Staff of the General Officer commanding the Mediterranean Expeditionary Force Became D.A.Q.M.G., in May. Appointed in July, 1917, hon. colonel of a battalion of the Cheshire Regiment. Appointed Grand Master of the Order of St Michael and George. Visited Italian front during Austria's attack in November, 1917 Took his seat in the House of Lords Feb., 19, 1918 Appointed Col.-in-Chief of the Cadet Corps in United Kingdom. Appointed Major in Feb. 1918. Received with much enthusiasm in Rome, May, 1918. Rode with the Guards on their entry into London for review by the King, March, 1919. Appointed Colonel-in-Chief of the 12th Lancers and Royal Scots Fusiliers, April, 1919. Became Freeman of the City of London in May, and High Steward of Plymouth in June. Started for a visit to Canada and U.S.A., August, 1919, and won universal popularity. Made several excellent speeches, and undertook many new duties. Had a separate home at St. James's Palace. Began, on March 16, 1920, a long tour to Australia, returning in October, after covering 45,000 miles and doing splendid service. Received a great welcome in London. Visited Glasgow in March, 1921. Appealed for Boy Scouts' Fund, and a large amount was received. Carried out with great success a long list of public engagements in 1921. G.C.S.I. and G.C.I.E. conferred on eve of a voyage to India, Oct., 1921. Welcomed warmly on his tour in India, Japan, and returned to England, June 20, 1922, Created a Knight of the Thistle on his birthday in 1922 Had a strenuous year of public service in 1923. Visited his Canadian ranch in September. In February, 1924, opened new science buildings at Mill Hill School, and performed many other public duties. Wembley Exhibition owed much to his enthusiastic support.

*Daily Mail Year Book for 1925.*

---

### *THE EDITOR'S OBSERVATORY.*

**Welcome Home.**

The Rt. Rev. Dr. Howells D.D., of The Niger Diocese arrived in town on Wednesday last; the Bishop, we learn, is preaching the Synod Sermon in the course of the month.

***Muses at the Altar?***

Mr. T. K. E. Phillips A.T.C.L., organist of Christ Church Pro-Cathedral, it is stated, is leading Miss Amblestone to the "United State" to-morrow, at Christ Church Pro-Cathedral

**"He is risen"**

"Sunday best" is the order of the Day to-morrow for all and Sundry in all Divine Services; it is hoped change of heart will eventually supersede all desire for pomp and vanity.

We wish our readers, a merry, pleasant, Easter Tide.

**Mr. J. T. Akiremi White "At Home"**

Mr. J. T. Akiremi White of White's Hall, Lagos, will be "At Home" to a select company on Easter Monday at his retreat White Lodge, Ebute Meta.

---

Mrs. E. B. Beckley of No. 53 Broad Street begs to announce that she has started cake-baking of all kinds; ever ready to serve!

---

ẸNIKEJI,

Aṣọ oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3, St. John *Street*, I Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

MISS GLADYS AYODELE WRIGHT attained to her 23rd birthday to-day. *Congratulations.*

## LABARI NIPA AREMO OBA.

### *H. R. H. The Prince of Wales.*

H. R. H. The Prince of Wales, Edward, Albert Christian George Andrew Patrick David

A bi Aremọ-ọba Gẹsi ni ọjọ 23 oşu *June* ni ọdun 1894.

A kọ ọ ni işẹ jagunjagun ninu Ọkọ *Osborne* ati *Dartmouth.* O jẹ enike i awọn meji ti o gba ẹbun ni ere Ọkọ-wiwa *Dartmouth Regatta* ni ọdun 1910.

A fi jẹ Aremọ-ọba Gẹsi (*Prince of Wales*) ni *Carnarvon* ni ọdun 1911. O jẹ oye akojẹ ninu Ọkọ ogun (*Midshipman*) ninu Ọkọ ti a npe ni *Hindustan.* Ọga Ọkọ na sọ nipa rẹ bayi pe :—

"Ni gbogbo akoko ti Aremọ-ọba yi nkọ ẹkọ labẹ on, o je alapọn enia gidigidi, ti o kun gbogbo awọn ti o ba-a lo, iba şe agbalagba tabi ọmọde, loju to bẹ, ti nwọn fi nwo o bi olokun enia."

O gba oye K. G ni *June* ọdun 1911. O gbe *Paris,* olu ilu awọn Faranse fun oşu melokan ni ọdun 1912, nibiti o ri anfani ati tubọ mọ ede Faranse siwaju, ati lati tubọ ni oye nipa ilu Faranse daradara. *President* (tabi ẹniti o dabi Ọba) awọn Faranse fun u ni oye ti a npe ni *Legion of Honour* ni oşu *July* ni ọdun 1912, ati *Croix de Guerre* ni oşu *October* 1915. Ni oşu Marşi, ni ọdun 1913, nigbati o fẹ lọ bẹ ile Germani wo, a sọ ọ di *Lieutenant.* O kọ ẹkọ ni Ile Ẹkọ Giga ti a npe ni *Magdalen College, Oxford.*

O şe işe akọşe rẹ ni gbangba, nipa fifi okuta ipilẹ Ile Ọlọrun, ti a npe ni *St. Anselmis Church, Kennington* lẹ lẹ ni oşu *June,* ni ọdun 1914. O lọ si oju ija, nigbati a njagun Ajakaiye (*The Great European War*) ni oşu Nofẹmberi 1914. O wa ninu awọn ti o jẹ Juman ọgagun nla ti a npe ni Sir John French. O şişẹ pẹlu itara ati bi akikanju okonrin, on si li ẹn ti o mu irohin ogun olokiki ni (*Battle of Neuve Chapell*) lati ọdọ Sir John French wa ile.

O balaga ni ojọ 21 oşu *June* 1915, o si şe ẹyẹ ọjọ na laipariwo. Ni oşu *July* ti o tẹle, Ọba Itali fi oye ti a npe ni ***Order of Annuroziata*** kan sara rẹ i. O lọ si Egipti ni oşu **Maşi** 1916, nigbati a yan a bi balogun labẹ Ọgagun nla ti a fi ẹgbẹ ogun ti a npe ni ***Mediterranean Expeditionary Force*** le lọwọ. A so ọ di 1 . A Q M.G. ni oşu *May* ọdun na. Ni oşu *July,* ọdun 1917, a sọ o di oloye ogun *Honorary Colonel* ti ẹgbẹ Ogun *Cheshire Regiment,* a sọ o di Babasalẹ *Grand Master of the Order of St. Michael and St. George.* O lọ si oju ogun ni Itali, ni oşu Nofẹmberi 1917, nigbati awọn ara ilu Austria nba awọn Gẹsi jagun.

O bẹrẹsi joko ni Igbimo nla ti ilu ni *House of Lords* ni ojo 19 oşu Fẹbuari, 1918. A fi jẹ oye *Colonel-in-Chief* ti ẹgbẹ *Cadet Corps* ti ilẹ Ọba Gẹsi (*United Kingdom*). A yan a bi *Major* ni Fẹbuari, ọdun 1918. A tẹwogba pẹlu ayọ nla, nigbati o lọ si ilu Romu ni oşu *May,* ọdun 1918. O ba awọn ọwo ẹgbe ogun, ti a npe ni *Guards* gun Ẹşin wọ ilu *London,* nigbati Ọba fẹ yẹ wọn wo ni oşu *March* 1919.

A yan a ni oloye *Colonel-in-Chief,* fun egbẹ, ti a npe ni 12th *Lancers* ati *Royal Scots Fusiliers* ni oşu *April,* ọdun 1919.

O gba ominira ilu *London* ni oşu *August* 1919, o si di *High Steward* ilu *Plymouth* ni oşu *June* na.

O lọ si *Canada United States* ni ilu Amẹrika ni oşu *August* ọdun kanna. Gbogbo awọn ara Amẹrika li o si fi ayọ nla-nla gba a. Ijoba pupọ ti o sọrọ daradara ti o jọnloju li awujọ, o si ti işẹ rere, ti o jẹ eyiti on tikalarẹ dasilẹ ti o si jọniloju.

O ni ile tirẹ loto ni afin Ọba ti a npe ni *St. James' Palace.* O lọ si *Australia* ni ọjọ 16, oşu *March,* ni ọdun 1920, o si bọ ni oşu *October* ọdun kanna. Gbogbo ibiti o rin de nigbana jẹ irin ọkẹ meji, o le ẹgbẹdogbọn *mile* (*45,000 miles*) Işẹ ti o si şe nibi gbogbo ti o de si dara. *London* si fi tayọtayọ tẹwọgba ati abọ. O bẹ ilu gbogbo wo ni oşu *March* 1921. O sọrọ kakiri fun iranlọwọ *Boy Scouts Fund,* o si ri owo pupọ gba si apo ẹgbẹ na.

Gbogbo işẹ ilu ti o ni lati şe ninu ọdun 1921, li o şe li aşeyọri.

A fi awọn oye G.C.I. ati G.C.I.E. ta a lọrẹ, nigbati o mura ati lọ si ilẹ *India* ati *Japani,* o si padabọ si ilẹ Gẹsi ni ojọ 20, oşu *June* ni ọdun 1922. A fun u ni oye K T. ni ojọ ibi rẹ ni 1922.

Lala işẹ pọ fun u ni ọdun 1923. O bẹ agbo Malu rẹ, ti o wa ni *Canada* wo ni oşu *September* ọdun na. Ni oşu *February* ọdun 1924, o si Ile Ẹkọ titun, ti a npe ni *Mill Hill School,* nibiti a o ma kọni li ẹkọ ọgbọn (*Science*), o si şe işẹ ilu miran Iranlọwọ ati ayan ti o şe nipa iran nla ti (*Wembley Exhibition*) ti a şi ni eşi, nibiti a ko oniruru ohun iyanu aiye yi jọ si, li o jẹ ki ohun gbogbo ti a şe nibẹ yori daradara.

***Daily Mail Year Book for 1925***

## LATI INU "IWE-ITAN ADUGBO EKO"

TI PROF. DENIGA ṢE.

*( A ko gbọdọ da a tẹ lai gba 'ṣẹ. )*

Itan ṣoki nipa ti awon Adugbo l'Eko ti Arẹmọ Ọba *King* yio gun Moto gba, pelu Gomina wa, ni ireni, ni agogo mẹwa arọ *Tuesday* ọjọ kẹrinla oṣu yi.

### MARINA (ẸHINGBẸTI.)

1. A npe e bẹ, nitoripe ibẹ ni ibi pataki ti a nda gbogbo panti ati ohun eri gbogbo si ni igba ailai li Eko.

### ITA TINUBU.

2. Ita nla yi, nibiti a gbe kọ Kotu nla si, ni a nfi orukọ obinrin Iyalode nla kan ti a npe ni Ẹfunroye Tinubu pe Ẹgba ni obinrin na, on si li a le pe ni *Boadicea* ti Eko ni igba lailai. Ọna Agbadarigi li o gba wa si ilẹ yi lati Abẹokuta wa. O nṣowo Taba ati iru nkan bẹ miran titi o fi di olowo nla. O ni ẹru pupọ. Ibiti ile awọn Ọlọpa wa nisisiyi (*The Lagos Police Force*) ni ile rẹ ti wa ri; ohun li a sọ pe o fifun ologbe Captain J. P. L. Davies fun gbese ti o jẹ ẹ. O kuro li Eko lọ si Abẹokuta ni *Tuesday* ojo 15 oṣu *April* ni ọdun 1856, ko si pada wa si ilẹ yi mọ.

### OPOPO-NLA.

3. Eyi jẹ ọna opopo pataki kan. O bẹrẹ lati ọdan, titi wa de Pearse *Square*, ni Oke Olowogbowo. O jẹ iwọn *mile* ọkan ati abọ ni gigun 1½ *miles*).

### ITA VICTORIA ỌBA OBINRIN.

4. Orukọ Ọba Queen Victoia ni a fi npe evi, ẹniti gbogbo aiye mọ ni "Victoria ẹni rere," nitori alafia ti o wa ni akoko Ijoba re.

A bi i ni ọdun 1819. O gun ori oye ni ọdun 1837. O ku ni ọdun 1901.

### ITA BALOGUN.

5. A sọ ibiyi ni oruko okonrin kan ti o nje Ajeniya, ẹniti oye rẹ je Balogun Eko. O bẹrẹ si lugbagba nigba aiye Ọba Akitoye, o si sa agbara rẹ ninu gbogbo ogun ti a ja nigbana.

---


## Unitarian Christian Church.

**EASTER SUNDAY.**

EXHORTATION MEETING.

5 p.m. Arapa Hall, opposite "Eko Akete" Offices

SUBJECT :—Christ's Resurrection in the light of Modern Thought.

All are welcome.



## ILE AGBE PẸKUN.

Bi o ba nfẹ posi ti o dara fun lilo nigbati akoko ba de, maṣe gbagbe lati lọ si ọdọ awọn Ọgbẹni wa wọnyi, nibẹ ni o ri oniruru posi ti a ti ṣe lọṣọ fun lilo; owo diẹ ni a nta wọn

Ranti maṣe gbagbe ki Ala jẹ ki ọmọ gbẹhin wa o.

Ile Iṣẹ

J. S. BAMGBOSE ATI J. SOARIES

*Builders and Contractors.*

No. 161, Igboṣere Road,
Lagos.


---


The West African Soap Co. Limited

APAPA, NIGERIA

*Manufacturers of*

**NEPTUNE**

PALE SOAP

**BUGLE**

PALE SOAP

**MAGNET**

CARBOLIC SOAP

will send Price Lists and terms to merchants upon application to

P.O. Box 522
Lagos
Nigeria

F 303

### H. R. H. PRINCE OF WALES' SPEECH
AT
THE ANNUAL CIVIL SERVICE DINNER IN LONDON.

"First-wicket stands are all the fashion just now. But when I look down the order of going in—I mean the toast list—(laughter) and see the great batsmen who are to follow me I feel it is not for me to try to emulate either Hobbs or Sutcliffe. (Laughter) Though I feel to-night that the wicket is an easy one, I shall not trouble you for many overs.

"There are two things I must say after the extremely kind way in which you have received this toast. The first is to tell you how glad I am to meet here to-night such a large and representative gathering of Civil servants, and to have this chance of establishing the same personal association with you as with the other three Services (Cheers.) I am delighted, too, to see representatives of the great Dominions with us. Their presence here makes this an assembly, not only of the State workers of Great Britain, but of the whole of the Empire. (Hear, hear.) The task of proposing the toast of H.M. Civil Service has fallen, very appropriately, to the Prime Minister I do not envy him his task, because it would be very difficult, if not impossible, to express in words the extent of the debt which this country owes to succeeding generations of Civil servant who, as Government follows Government, have never failed to serve them with unquestioned loyalty and efficiency. (Cheers.) It is not for me to enlarge on this subject to-night. I could not, however, sit down without paying my tribute to a Service which, with all my fellow-countrymen, I recognise as great in every sense of the word. (Cheers.)

"The other thing I want to say concerns the sport of the Service and your schemes for organizing it on a solid basis. I am going to risk what I should call a very silly old pre-war joke—so old that I cannot remember it (laughter)—it was only told me to-day. It is that the Civil servants are like the fountains in Trafalgar Square—(laughter)—because they play from 10 till 4." (Laughter.)

It is just as absurd as the old saying, "all work and no pay," etc., is true. I certainly think Civil servants should play—not necessarily from 10 to 4. (Laughter.) Perhaps I can in a way put myself in your position, because we do not always feel in the best of tempers and up to all our work. If we get a chance of a game or of getting out, it cures us better than anything else. (Hear, hear.) Those who work at mental occupations for their livelihood do their work all the better if they can keep themselves physically fit, and if any of you, any days of the year, can play from 10 to 4 (laughter), all the better.

*From the "Times" Weekly Edition of 26th February, 1925.*


**Mr. T. Harding,**

*METHODICAL TAILOR.*

ARALAMỌ WORKSHOP

216, BAMGBOSHE STREET, LAGOS.

*PERFECT FITTING GUARANTEED.*

TERMS:—*CASH WITH ORDER.*

## White's Golden Male Tonic.
(DOUBLE-STRENGTH)

Whenever a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs. Now while it is true that many women suffer from disease yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. *White's Golden Male Tonic* (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs

**Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.**

*The Reliable Dispensary, 41 Offin Road, Lagos.*

N.B. NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.

SHAKE THE BOTTLE.

AREMỌ FUN ỌKUNRIN

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o nję pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo Arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

N.B.—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo ligo mejimeji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price ten shillings (10/-) per bottle.


## NOTICE.

IN THE MATTER OF THE ESTATE OF

**SAKA AMODU OLOWU,**

(DECEASED).

*Pursuant to the statute 22nd and 23rd Victoria Chap. 35.*

NOTICE IS HEREBY GIVEN that all creditors and other persons having any debts, claims or demands upon or against the Estate of SAKA AMODU OLOWU, late of Binuyọ Street, in Lagos, Nigeria, who died on the 24th day of December, 1924, intestate and Letters of Administration of whose personal property were on the 7th day of March, 1925. granted by the Supreme Court of Nigeria to me, the undersigned, are hereby required, to send in particulars of their debts, claims or demands in writing to me at my residence, at 50, Victoria Road, Lagos, on or before the 15th day of June next (1925) after which day I will proceed to pay and distributed the assets of the said estate among the parties entitled thereto, having regard only to the claims of which I shall then have had notice and that I will not be liable for the assets or any part thereof, so distributed to any person or persons of whose debt, claim and demand I shall not then have had notice.

And all persons indebted to the said estate are hereby required to make immediate settlement of their accounts.

Dated at Lagos, this 10th day of March, 1925.

YAYA AMỌDU OLOWU,
*Administrator.*

**EKO AKETE**

Eko, Saturday, April. 11, 1925.

## A LỌ F'OJU KAN ỌBA LONI
## A LỌ F'OJU KAN ỌBA ;
## OYI BIRI KÒKÒ,
## A LỌ F'OJU KAN ỌBA.

Irufẹ orin to yẹ gbogbo ilu ni kikọ ni akọgbadun bi apọnrọn ti nsọ tẹnu rẹ ni ireni leyi fun pipade ẹni a ti nperi nì, ani Arẹmọ Ọba King, a-bo-kọ̃lọ gbọgbọrọ ; ẹ sa gbọ ogidi-nleje orukọ. Jagun na :—Edward Albert Christian George Andrew Patrick David ; ẹ o ri pe Ọmọ-ọba na yio pidan meje ti ọdẹ npa nigbati o ba de gẹgẹbi orukọ rẹ ti jẹ meje ; idayi ireni gbogbo Eko a ti gbojikan fun igbe kãbọ̀ ! kabọ ! ! kabọ ! ! ! ti a o ma da loporo lu Arẹmọ na. Lati igbati a ti ta Asia Gẹsi si ilẹ yi, a koi ti ri pe ibatan ki ibatan Ọba King ti'le t'ọna wa bẹ ilẹ yi wo ri, ki a ma tilẹ ṣẹṣẹ sọ ti odidi Aremọ : o si yẹ ki a dupẹ lọwọ Ọlọrun gidigidi fun mimu wa ri anfani iru eyi papa ni aiye isinsinyi ; ẹniti a nreti rẹ yi jẹ Ọba lọla, nitori bi ewe gbo, to si rẹ̀, ti Ọba King wọ àjà, ẹniti ade gbigba kan ko ju Arẹmọ yi lọ mọ—A f'erin-musẹ-ṣ'ọkọ-oge.

Ninu awọn ọmọ iya rẹ ti o to obinrin nini, on nikan lo ṣi ku ti koi ti ṣe bẹ̃ ; eyi si jẹ ẹkọ daradara lọna tirẹ pe ko si igbati a daṣọ ti a ko ri'lẹ fi wọ́, ati pe tutete l'obinrin ki iṣe ohun ti a le ṣe wamọtipọ si, nigbati oluwarẹ ba ri pe irufẹ yiyara bẹ̃ le jẹ idiwọ diẹ fun on, nipa bibojuto iṣẹ ti a fi ran a lati ode ọrun ; o jẹ iṣẹdalẹ Ilu Gẹsi pe bi Ọba kan ba wà lori itẹ, ki Arẹmọ rẹ ṣ'apa kitipo lati bẹrẹ si mu irin ajọ pọn lọ si oriṣiṣi ilu ti o wa l'okere, iba ṣe awọn ilu to wa labẹ asia baba rẹ ni, tabi awọn ilu miran ; nipa bayi nigbakigba ti ipo oye nla yi ba kan, ki yio je ọgbẹri nkan pupọ ti o ni lati mọ nipa ilu okere. Nigbati Ọba King Edward koi ti wọ àjà, bayi ni Arẹmọ ẹniti o jẹ Ọba wa nisinsinyi nkakiri oriṣiriṣi ilu. Arẹmọ ti a si nṣe af'oju s'ọna rẹ ni ireni yi ti lọ si ilu *Japan*, *America* ati awọn jakanjakan ilu bawọnni ri, on nikan ni yio si kọ bẹ ilẹ yi wò gẹgẹbi Arẹmọ Ọba King lati ọjọ ti Ilu Eko ti di ti Gẹ̃—.

Bawo ni ayọ ilu iba ti pọ to o, bi o ṣe pe ọwọ ilu tẹ eku idà ti a ti ntọrọ lati ọjọ njọ yi wa ? Ṣugbọn gẹgẹbi a ti wi ni ọsẹ to kọja, o yẹ ki a tujuka ki a si gba Alejo nla na t'ọwọ t'ẹsẹ, ki a ma si ṣe jẹ ki ẹnikẹni ko janin-jain tirẹ wa ba ni. Gẹgẹ bi ilu ti ma kun ṣọṣọ lati ireni lọ, ẹbẹ ohun meji mẹta ni a fẹ fi siwaju ẹnyin enia wa.

Ekini :—Ki awọn ọlọmọde maṣai ṣe itoju wọn gidigidi, aiye ti di aiye mọto,

Ekeji :—Ki awọn Owĩwà ( eyini ni awọn ti o nsaba nfi mọto onimọto ju ẹra ) fi ọ̀dẹ̀ pupọ si wiwa mọto, ki nwọn ma ba lugbadi ẹsun-apania ninu ofin.

Ẹkẹta :—Ki awọn oworan gbogbo kiyesara awọn firi ni'di ọkẹ ; nigbati nwọn ba nlọ woran, bi bẹkọ apo ẹlomiran le di fifi ọbẹ ja danu lọ patapata porongodo.

Ẹkẹrin :—Ki ẹnikẹni maṣe joye a-tan-ni'lef-'ara-fun-wọn-bu, eyini ni pe ki o ma si pe gbogbo awọn ara ile kan nṣigbo lọ woran laiku ẹnikẹni sẹhin ; jamba awọn kolekole ọsan gangan isinsinyi ko ma sẽ fi ọwọ yẹpẹrẹ mu.

Ẹkarun :—Ki awọn abiamọ tọju ọmọ wẹwẹ wọn, ki o ma si pe a nṣe gbajare ọmọ kan rara.

Ẹkẹfa :—Ki o ma si ẹṣẹ a ngba ẹnikẹni ni'pakọ, ki a si ma ti oluwarẹ lọ gbọngbọn lọ si Ṣabu awọn akẹran fun ẹṣẹ kọkan.

Lakotan ẹnyin ara ilu, ẹ jẹ ka yọ fun irufẹ ibẹwo ti Arẹmọ yi mbọ wa bẹ wa wo ; talo ro nkan nla bayi si Eko ni ẹnu ọdun kẹta tokọja ? Bi o ti wu Oluwa lo nṣọla.

Laisi aniani, igbagbọ t'awa papa ni pe o ṣi tun ku ohun ribiribi miran ti Olodumare ki yio ṣai fi han wa lọna ara lati rẹ̀ ilu lẹkun "bo d'ọla" ; Ẹ ku'pamọ !

## *Open Letters.*

No. 53.

To His Royal Highness,

EDWARD ALBERT CHRISTIAN GEORGE ANDREW PATRICK DAVID,

*Prince of Wales*

Government House

Lagos, Nigeria.

Your Royal Highness,

Words fail me to express very adequately how jubilant are the loyal and dutiful subjects of His Majesty the King in this great Dependency are, in welcoming Your Royal Highness to our shores: it is an open secret to say that since the British occupation of this country on August 6 1861, during the reign of King Dosomu, we have never been privileged nor has it fallen to our lot to record the visit of any members of the Royalty, beyond the seas, let alone that of an Heir-Apparent to the British Throne such as Your Royal Highness are, to this part of His Majesty's Dominions.

Writing from memory I believe that of all the colonies in British West Africa—and in this I am open to correction,—our sister colony of Sierra Leone alone was the first to enjoy the Royal visit in the year 1860 of His Royal Highness Prince Alfred, an occasion which was very significant in the annals of that ancient, loyal and progressive peninsular; significant in that one of our own *flesh and blood* in the person of G. W. Johnson, popularly known in after years as the Reversible Johnson, father of the Egba United Government, came under the notice of the Royal Visitor with the happy result that the young African became as it were, the protégé of His Royal Highness who eventually sent him to Europe for more training during those halcyon days.

To say Sire, that it has given us unqualified pleasure nay, a unique opportunity to see Your Royal Highness face to face, as a man talketh to his friend—to borrow a theological terminology, is to give expression to poverty of language and we have that confident assurance, having regard to Your Royal Highness's social disposition and sportsmanship that in Your Royal Highness is found that magnanimous spirit as depicted by Cowper:—

"Fleecy locks and black complexion
Cannot forfeit Nature's claim;
Skins may differ, but aspirations and affections
Dwell in *Black and White* the same, (Italics, mine)

The only regrettable episode is the rift in the political life of this country occasioned by the disfavour into which the accredited HEAD of our African community has fallen in the hands of "the powers that be" during the last five years, and would to GOD, Your Royal Highness sympathise with your people in this their present predicament.

During Your Royal Highness's stay in our midst and throughout Your Royal Highness's 20,000 mile tour, may success in its thousand fold attend and crown Your Royal Highness's ingress and egress.

*Salaam-ma laikun!!!*

EKO AKETE

## *PRINCE OF WALES—AREMO OBA.*

[ *Lati owo* ATARI-AJANAKU. ]

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bere f'oji,

Ni ireni, eyini ni, ni ojo merin l'oni, ti ko ba si dasi, Aremo-oba wa Ilu Oyinbo yio gun'le si Ebute Ehingbeti tiwa kanna yi larin ayo, ilu ati ijó. Ibikibi tabi ilukilu ni *Nigeria* ti o wu ki o le lo lehinna, Eko ni o koko fi ese te, nigbati akoko ba si to fun u lati pada lo si Ilu Oyinbo, erupe Eko kanna yi ni yio fi ese te kehin. Eyi je apere nla ti o tubo fihan onile ati alejo wipe Eko ni *Alpha* ati *Omega*, ibere ati opin gbogbo ilu ti o nbe ni *Nigeria*.

Aremo-oba, Aremo-oba; ta tile ni Aremo-oba yi, ati kini o tile da on pelu Eko po? On nikan sa ko ni Aremo-oba ti o wa ni Ilu Oyinbo; Aremo-oba Jamani wa, ti eniti o wa ni ipo Oba Faranse ati ti Amerika wa, Aremo-oba Itali wa, ti Oba Bolgaria ati ti oniruru Oba ti o wa ni ile Enia Funfun wà pelu. Nje bawo ni *Prince of Wales*, Aremo-oba Ilu Gesi ti ri si wa, ipo wo ni o wa si wa?

Nitoto, a ko mo o ri; sugbon, itakùn ti o so agbè l'o so elegéde! *Queen* Victoria Ologbe, Oba rere, eni rere, li akoko eniti aiye toro, ti aiye r'oju, ni awa mo daradara bi eni mo owo: ati gege bi ore Dosunmu, Oba wa.

*Queen* Victoria yi ti o ba Oba Dosunmu da majemu ore, ki a to fi ayo ati inu didun gba asia Ijoba Gesi ni ilu wa, ni o bi Oba Edwodi keje, *King Edward VII.*, Edwodi Oba yi, ni o bi Oba Joji karun, *King George V.* ti o wa lori oyè nisisiyi, Oba Joji yi si ni baba *Prince of Wales*, eniti a nreti bibo re ni ojo merin loni. E ko wa ri i nitoto wipe, Itakùn ti o so agbè l'o so elegéde!

Ina ku fi eru b'oju, ogede ku fi omo re ro'po: *Queen* Victoria ko ku a-ku-run, beni Oba Dosunmu ko sai fi omo si aiye! Omo-omo omo *Queen* Victoria ni o nbo, ni gbogbo ilu nro keke yi, nibo ni Eleko omo Dosunmu wa? Olola Hugh Clifford, Gomina, enyin ni a nbawi!

Irin-ajo kakiri ilu ko se ohun akotun fun Aremo-oba Ilu Oyinbo. Nigbati Edwodi, baba Oba ti o wa lori oye nisisiyi wa ni ipo Aremo-oba, beni o lo si ilu Itali ati Spain ni odun kerindiladorin ohun, (1859): Canada ni odun ti o tele e, Palestine ni odun keta ti o tele e, Egypt ni odun keje ti o tele e, o si lo si ilu India ni adota ti o koja, (1875): o si wa nibe fun osu merin gbako. Pelu ijo ati ayo ni nwon gba a s'owo, gba a s'ese ni gbogbo ilu wonyi, igba kan soso sà ni a gbo wipe ewu wu u, eyini ni, ni odun karundi-logoji ohun, (1890) l'ona ilu Brussel, nigbati odomodekunrin kan ti oruko re nje Sipido ta a ni ibon, nà ireti ati pa a!

Lẹhin ti Ẹdwodi si gba adé tan, o lọ si Portugal, Italy ati Paris ilu awọn Faranse, ni ọdun kẹjile-logun, 1903: on pẹlu iyawo rẹ si lọ ki Kaiser ni Jamani, ni odun kẹrindi-logun, 1909.

Bi Edwodi Ọba ti lọ kakiri ilu bayi, bẹni Arẹmọ rẹ, Albert Victor na rin jina, ki titan to de si i ni ọdun kẹtale-lọgbọn, nigbati o di ẹni ọdun mejidi-lọgbọn! Ikú rẹ ni o jẹ ki oye Ọba kan aburo rẹ Joji, Ọba ti o wa ni ori ovè nisisiyi; iyawo afesona, *Mary of Peck*, ti Albert Victor, Arẹmọ-ọba Ẹdwọdi keje nfẹ nigbana, ni Joji Ọba, aburo rẹ gbe ni iyawo lẹhin iku ẹgbọn rẹ; iyawo na ni o si di *Queen* Mary loni!

Lẹhin iku Albert Victor, iku ti o sọ Joji di Arẹmọ-ọba li akoko na; ati gẹgẹ bi Arẹmọ-ọba, Joji papa ko s'Jai lo si ajò, nitoripe gbogbo ilu India ni o fọ kiri patapata ni odun kọkandi-logun, ki o to gba ade Ọba ni ọdun kẹrinla ẹhun.

Bi nwọn ti rin irin-ajo tó ni, ko si ẹnikan ṣoṣo ninu wọn ti o daba lati wa si Eko, tabi ilukilu miran ni apa ihahin, bikoṣe Arẹmọ-ọba ti o nbọ nisisiyi. Ẹni ula ni ọmọ na, orukọ meje ni on nikan ṣoṣo si njẹ!

Awọn orukọ na niwọnyi:—

1. Edward
2. Albert
3. Christian
4. George
5. Andrew
6. Patrick
7. David.

A bi *Prince of Wales*, Arẹmọ-ọba ni ọdun kọkan-le-lọgbọn ẹhun, (1894.) Arẹwa ọmọ ni nṣe, ati a-du-fẹ awọn obirin, ti o nkọ Iwe-ifẹ si i ni ọpọlọpọ ibiti o ti de, bi Amẹrika ati ilu miran. Aburo rẹ okunrin ti gbeyawo, eyi obirin si ti nfi "ọwọ ṣe esun;" sibẹsibẹ, apọn ni on papa ti o jẹ ẹgbọn wọn wa titi di oni!

Laisi ani-ani, ati gẹgẹ bi Ọba ẹhin-ọla, ẹrù kekere kọ ni o wa niwaju *Prince of Wales*. Bi ilu yi ti ṣe le dara, ti tọhun ṣe ma wa ni irẹpọ, ti ija ati aso ki yio si si ni gbogbo ilu ti o wa labẹ Ijọba, jẹ ero ti o ni lati wa li ọkan Ọba oni, ati ọkan Ọba ọla nigbakugba; Ọba ti ko ba si wipe "on ṭe," ipa ni yio fi ri aye jẹun wọ'nu.

Pe *Prince of Wales* Arẹmọ-ọba ni ifẹ nla si gbogbo enia ti o wa labẹ Ijọba baba rẹ, ati dudu, ati funfun, tabitabi ko si ninu eyini.

A nlọ si India ni o, a nlọ si Jamani ni o, a nlọ si ilu Faranse ni o, a nlọ si Amẹrika ni o, ko si eyiti o ni ewu ati ibẹru to ati wa si Eko tabi *Nigeria* ninu wọn, papa n tori irọ ti awọn Oyinbo ilẹ yi npa ranṣẹ si Ilu Oyinbo nipasẹ wa, ati nipasẹ enia ti o wa nibẹ.

Bi Oyinbo fẹ ya aworan wa ranṣẹ si ilu wọn, dipo eyiti nwọn iba fi enia atata ranṣẹ, aboyun ti o san ponpodọ lasan mọdi, ti irun ori rẹ ri wuruwuru, ti o nlọ igbado tabi ti o ntẹ ẹyin ni abule oko kan, ni nwọn ma fi aworan rẹ ranṣẹ wipe on ni enia pataki julọ ni Eko tabi ni gbogbo *Nigeria*.

Iyokù di iregbe, ni ojo kan ni Ilu Oyinbo, Oyinbo kan ti o ti ṣe iṣẹ Alufa Ojiṣẹ Ọlọrun ni ilẹ yi ri ni akoko kan, nsọ asọye bi ilu Eko ti ri fun awọn ẹgbẹ rẹ. O ni, o ṣoro ki o to ri obirin kan ṣoṣo pere li Eko l'ai gbe ọmọlangi pọn, o ni, ejo ati ọni nje kiri ilu, ati oniruru isọkusọ miran. Nigbati Oyinbo yi pa oniruru irọ rẹ tan, ologbe Felicia Ayẹdele Wright lọ ja a ni koro, to si sọ fun gbogbo apejọ na pe, ni Eko ibi ti on ti wa, ko si iru nkan to jọ eyi ti Oyinbo yi wi nibẹ, ati pe nitori na gbogbo ọrọ ti Oyinbo lo pe ara rẹ ni ojiṣẹ Ọlọrun yi sọ, jina si otitọ.

Melo ni a o ka ninu gbogbo isọkuso ti Oyinbo miran ti sọ, ati isọkuso ti nwọn nsọ lowọlowọ si wa lara? Ewo ni ko ni to lati ba ẹni ti ko ba de ibi ri l'ẹru nibẹ? *Prince of Wales*, Arẹmọ-oba ko ni ṣa lai gbọ ri pe "Ile iku Oyinbo" "*White man's grave*" ni suna ti awon Oyinbo fun ilẹ yi. Sibẹsibẹ, o tun mu ẹna pọn lati odidi ori itẹ rẹ, nitori ati wa mọ "Ile Iku Oyinbo" "*White man's grave*", ati awa Enia Dudu alaye to wa nibẹ, ati Oyinbo titi de Gomina, ti awa Enia Dudu, nino anu wa, ti so Sokurọ mọ lọwọ, ti ko si jẹ ki wọn ti ku.

Eyi fi ifẹ nla ti Arẹmọ-ọba ni si wa han, adura wa si ni pe ki o de si arin wa pẹlu alafia, ki o si pada sile pẹlu alafia; ikọ ko nkọ ejo l'ẹsẹ.

Nigbati Arẹmọ-ọba ba gun'lẹ ni agogo mẹwa arọ ọjọ mẹrin oni, lẹhin ti awọn Ṣoja ba ti ki i tan yio wọ Mọto lọ si Ẹbingbẹti, ita Balogun, Broad Street, ita Tinubu, ọdan, ki o to lọ si ile Ọba, *Government House*. Ni ago mẹwa abọ, a o mu Onidajọ agba ati Iyawo rẹ, ati awọn Onidajọ abẹ Bisọpu, awọn Aṣoju Ilu Oyinbo ajeji ati Iyawo, mọ Arẹmọ-ọba; a o mu awọn to ku mọ ọ ni ago mọkanla ku iṣẹju mẹdogun. Lẹhinna, gbogbo iwe iyẹsi ti o ba wa nilẹ, a o ko wọn fun Arẹmọ-ọba, yio fi esi kukuru si ti Ijọba, yio si ṣe wọnka esi yoku ki oto fi lu silẹ. Ni ago mẹrin, Arẹmọ-ọba yio lọ wo ere Ẹṣin l'ọdan titi di ago mẹfa abọ, ni ago mẹwa alẹ ku iṣẹju mẹdogun, Ọkọ mẹta yio ma yin Rọkẹti.

Ni ọjọ alaruba ni ago mẹwa owurọ, Arẹmọ-oba yio fi ipilẹ okuta Christ Church Cathedral le'lẹ. Ni ago mẹjọ alẹ kọja iṣẹju mẹdogun, Dina nile ọba; ni ago mẹwa abọ alẹ ọjọ kanna, yio ko si Ọkọ rẹrẹ o di Kano. Yio de Kano ni ọjo Jimọ ni ago mẹrin ku iṣẹju medogun; ni ago marun abọ yio rin ilu Kano ka, ni ago mẹjọ alẹ koja iṣẹju mẹdogun, Dinna nile Ajẹlẹ Kano. Ni Satide, ago mẹjọ arọ, yio lọ si *Durbar* ni Kano; ni ago marun abọ irọlẹ, yio gba Bọlu ti a npe ni *Golf*; ni ago mẹjọ alẹ koja iṣẹju mẹdogun, Dina nile Ajẹlẹ, ni ago mẹwa oru, Rọkẹti ati Ijo *Durbar* ti Ọyọ di agogo meji ọsan Monday, ọjọ mẹwa ooi

Arẹmọ oba yio kuro ni Ọyọ ni ago marun koja iṣeju mẹdogun ọjọ kanna, yio pada si Eko ni Tuesday tabi Atalata ọjọ mokanla oni, ni ago mẹfa aro ku iṣeju mẹdogun; ni irọlẹ ọjọ na ni yio lọ wo awọn ọmọ Ṣukuru ni ọdan, ni ago marun ku iṣeju mẹdogun; ni ago mẹjọ alẹ koja iṣeju mẹdogun, Dina ati Ijo nile ọba. Ni ago mẹwa arọ alaruba ijọ mejila, Arẹmọ ọba yio wọkọ lọ s'ile rẹ ni ilu oyinbo.

A ni ki Gomina ṣe *Durbar* tabi apejo nla ti awọn ọba ilẹ Yoruba fun Arẹmọ ọba ni ilẹ yi dipo Ọyọ, Gomina kọ, ko buru, ẹran lo nmu ni jẹ idin; ibikibi to wu ki Gomina le wipe on nfẹ ṣe *Durbar* fun Arẹmọ ọba, lilọ ni o yẹ kio jẹ fun gbogbo wa, ko nṣe nitori ti Ọlọla Hugh Clifford, bikoṣe nitori Arẹmọ Ọba papa.

Kini iba ti dun to, bi o ṣe pe ilẹ yi ni Gomina fi *Durbar* si; ọtọ ni awọn ara Ọyọ papa ti ko de ilẹ yi ri ni iba gbadun anfani ati ma Eko, ki a ma ṣe wipe Arẹmọ Ọba; ẹkọ nla ni nwọn iba si ri kọ nibi pẹlu.

O to ọdun melo kan nisisiyi, ara Ọyọ kan to wa wa lati rohin ohun iyanu, ati mawo nla, ti Oyinbo ṣe si omi ọsa. Awokẹkẹ wa ( *Rickshaw boy* ) ara Ọyọ yi tẹnubọ irohin oni "Ọga, ba ba ma sọrọ, ka sọrọ ṣin an, Oyinbo a ma na' wo ọ-jọ; aduru gbogbo omi ọsa to nbẹ nilẹ yi, Oyinbo ṣin bu'yọ ja gbogbo ẹ, Kai! o ti Alafin Ọyọ, ko le ṣe." Ẹ mṣe rẹrin, ko ye ara Ọyọ yi ni; ẹ ṣebi Oyinbo lo bu iyọ ja omi ọsa, ko mọ pe ola Ọlọrun ni. Ani, bawo ni iba ti dun to, bi o ṣepe d po eyiti Eko fi kilọ si Ọyọ fun *Durbar*, ko jẹ pe ara Ọyọ lo nbọ nilẹ yi, ṣe ọpọlọpọ ara Ọyọ niba ri aye mọ pe Oyinbo kọ lo bu iyọ ja "gbogbo omi ọsa to nbẹ nilẹ yi".

Iyato pupọ ni Arẹmọ Ọba yio ri ni ilẹ yi pẹlu ilu Oyinbo. Bi apẹrẹ yio ri pe iyatọ nla lo wa larin Ṣọṣi *St Paul's Breadfruit* ti ile yi, ati *St. Paul's Cathedral* ni ilu oyinbo; larin Ṣọṣi Aguda ti ilẹ yi ati *Brompton Oratory Roman Catholic Church* ti *South Kesington* ni ilu oyinbo; yio si ri iyato pupọ larin *Bank of British West Africa* ti ilẹ yi ati *Bank of England* to wa ni *Thread Needle Street* ni ilu oyinbo, yio ri iyato to wa ni isọ ẹlẹja ti Ita Faji ati *Billingsgate Fish Market*, isọ ẹlẹja ti ilu oyinbo; yio ri iyatọ pupọ larin *Nigerian Railway* pẹlu *The Great Western Railway* ti ilu Oyinbo; larin Kereni Alagbeko ( *Suspension Bridge* ) ti Jẹbba ati *Launbeth Railway Suspension Bridge* ni ilu Oyinbo; ju gbogbo rẹ lọ, yio ri iyatọ nla nla larin *Government House* l'Eko, ati *Buckingham Palace* ni ilu Oyinbo.

Nitori eyi pataki, ati lati le fi ifẹ ( *loyalty* ) ati ẹwọ ( *respect* ) wa han fun ọba Gẹsi, o tọ, o si yẹ jojo lati yẹ Arẹmọ Ọba si gẹgẹ bi ipo rẹ, o yẹ ki a gba a s'owọ, s'ẹsẹ, a si tanma pe gbogbo ilu yio ṣe be gẹgẹ, ṣugbọn ti o ba ku diẹ kiun sibikibi, ẹjọ Gomina papa ni, nitori lati igbati a ti nfi oju s'ọna fun Arẹmọ Ọba, ti Ilu ti yan Igbimọ ti Colonel Moorhouse ati Gomina si ti tu Igbimọ ti Ilu yan ka, nipa yiyan Igbimọ miran, to fẹrẹ kun fun kiki Oyinbo, lati igbana titi di isisiyi, Gomina tabi Igbimọ ti Gomina yan, koi pe Ipade gbo-gbo-gbo kan, lati sọ fun Ilu bi n'kan ti nlọ si, tabi lati bi Ilu jiroro pe, nijọ ti Arẹmọ Ọba ba wọ ilu, ati titi yio fi pada lọ, bawo, bayi, lo yẹ ki Ilu ṣe.

Nigbati Gomina tabi Igbimọ rẹ fun Arẹmọ Ọba ko ba si ṣe eyi titi Arẹmọ Ọba yio fi de, ariwo bi iru eyiti oja nṣe lo ma pọju lọjọ na *for want of instruction and organization*.

Ilu baje. Ina ilu ko dun; koi ju oṣu mẹdogun ti Ọlọla Hugh Clifford wọ ilẹ yi, nigbati o d'ori Ilu k' odo, nipasẹ ọrọ Eleko. Kini Eleko ṣe?

L'atọkọ Ijọba wipe nitori awọn janma fi Abibu Oki jẹ Balogun wọn, nwọn si mu to Eleko lọ, nitori na Mr. Henry Carr ṣa orukọ enia mẹtala ti Ijọba pe lati fi ọrọ Eleko han ki o to da a duro.

Meji pere ninu awọn mẹtala yi lo ni ki Gomina fi oju ano wo Eleko, awọn mọkanla iyoku ni ki Gomina rọ o l' oye. awọn bi melo kan ninu wọn ni ibatan Eleko ( royal family ) ni awọn nṣe, aldikowa ọmọ ateru d' ẹru ọba to ti jẹ l' Eko ṣiwaju Dosunmu ni nwọn nṣe.

Lai dena pẹnu, Ilu di le labẹ opagun ọlọla Loya Shyngle, Gomina si fi Eleko s ipo pada. Ija Imale to ti wa nilẹ tipẹtipẹ, nwọn ni nitori Eleko fi ọwọ si oye Balogun Abibu Oki ni ko jẹ ki ija na pari, lẹhin ti Eleko si yọwọ kuro nibẹ yi nkọ, ti Onidajọ Ọlọla Van der Muellen ṣe idajọ ija Imale, ti kotu onidajọ mẹta pẹlu *His Honour the Chief Justice*, Onidajọ agba si gbe idajọ Van der Muellen lesẹ, ṣe Eleko ni ko tun jẹ ki ija Imale pari mọ lẹhinna? Awọn ọlọtẹ, awọn alawigbo gan ti ko jẹ ki ija Imale pari, awọn jandukú to tẹ ipa si idajọ Van der Muellen, awọn alagidi to fi oju tinrin idajọ kotu onidajọ mẹta, awọn kanna ha kọ ni ọrẹ Ijọba loni, bi eti didi tabi omugọ lo mba Ijọba wa ja labẹ Ọlọla Hugh Clifford ni o, lati ma ka awọn alagidi bẹ si enia pataki ni Ilu sibẹsibẹ, awa ko mọ.

Agbako keji ti Eleko ko lowo Sir Hugh Clifford ni nipasẹ ọpa to di iyọrọ to bo t' olori t' elesi wọn. Lati ọdun karun na ni Gomina ti da Eleko duro, gbogbo Ilu si bẹ titi, o si dabi ẹnipe bi ẹbẹ na ba gba eti ọtun wọ 'le o ngba ti osi jade.

Ibaṣe pe Oyinbo ko ni ọba ni Ilu wọn ni, a ba wipe boya iyẹn ni ko jẹ ki nwọn mọ iyi ọba ilu miran; ṣugbọn nwọn ni ọba, nwọn jẹ orilẹ ede to nbu ọla pupọ fun oba wọn. Nijelo, ni adele Gomina kan, *Lieutenant Governor* A. G. Boyle ba Eleko wijọ pe o ni lati duro ti o ba nba on sọrọ; ni ọdun karun to koja ẹwẹ, ni Ọlọla Hugh Clifford nfi a-wi-da-'bọ wipe, "*The Eleko, threw himself into the arms of the most seditious and ignorant of the malcontents Mukamedans, and cajoled by their flattery, addres-*

*ed letters to the Government headed "Kings Palace" assuming a position to which he had never before pretended.'* Itúmọ isọkuso ti ọlọla Hugh Clifford yi sọ ni pe, "Eleko gbe ara le awọn ọlọtẹ Imale to nta kanrangbọn si Ijọba, awọn ọlọtẹ Imale yi si fi Eleko di elekuru tobẹ gẹ to fi gbaghe ara rẹ de ipo ti o fi nkowe si Ijọba pe on wa ni "Afin Oba", ipo ti kọ şeşi wi nigbakugba kan siwaju ri pe on wa".

Bi ko ba si aifioipeni, ati aifienia pe enia ti ara oko fi usar bantẹ wo'lu, irufẹ A. G. Boyle yen kẹ. a wipe ki Eleko dide duro ti o ba nba on sọrọ; Ọlọla Hugh Clifford papa a si ma sọ ọro alufanşa bẹ si odidi ọba l ra a wipe on nşe nkan iyi. Ki a mu ti a ye oyinbo kuro ati wipe awọn mejeji jẹ aşoju ọba, ola eniti a bu fun wọn, nşe ni a ba wipe ki awọn Ibiga lo şẹ wọn ni kan hin. (*have them poisoned*) ki a si fi igi gboro ha wọn lẹnu na ti nwọn fi sọ isọkuso si oba lara, şugbọn gẹgẹ bi aşoju ọba, pelu irẹlẹ ati ọwọ pupọ ni a fi uso ni sisiyi pe, isọkusọ ni A. G. Boyle ati ọlọla Hugh Clifford sọ nipasẹ Elẹko. Eyi ti awọn mejeji sọ a nwipe ko dara yi. Ọlọla Lọya Kitoyi Ajasa to pe Eleko ni "oku igi" nkọ? O ku Lọya Ajasa pẹlu ọkan rẹ, o ku Lọya Ajasa pẹlu Ọlọrun; adabi awọn aşiwaju rẹ ba pa a ni itan fun u ri pe nwọn pe Gezo ol a Dahọmi ni "oku igi" ri.

A ngbọ ọro kan nipasẹ awọn Onifila funfun, şugbọn a ko gba a gbọ. A ngbọ pe Onifila funfun to wa ni ipo ẹhin patapata ni Ijọba ngbero lati fi han *Prince of Wales* bi aşiwaju awọn iyoku, nitoripe Eleko ti fi fila funfun da a lọla şiwaju akoko ti pupọ ninu awọn Onifila funfun ọga rẹ j'oye.

Ti o ba şe pe bi enia ti pẹ ni işẹ ọba to lọ fi udi ọga, laibikita fun ipo rẹ ọpọlọpọ lebira ati mẹsinja niba jẹ ọga *Chief Clerks* pupọ. Bẹ gẹgẹ ni ipo awọn Onifila funfun ri. Ki a wipe ana alana ni Eletu Odibo şẹşẹ j'oye, on ni aşiwaju awọn Onifila funfun to ku nilẹ nsisiyi, a si gba gbogbo awon Onifila funfun ni imọran pe ki nwọn maşe jẹ ki enikẹ i fi nwọn di elekeru. Ibiti a ba pe ni o i, a ko gbọdọ fi tẹlẹ.

Nibo ni Eleko yio wa nijo ti Arẹmọ Ọba ba wọ Ilu? O yẹ ki gbẹdu fohun nijọna ni Iga Idunganran. O yẹ ki Gomina mọ pe ori lo duro fun agbọn mu 'mi, a si bẹ ẹ pupọ ki o fi Eleko sipo ki o to to akoko na. Bawo ni yio ti dun to nigbati Arẹmọ Oba ba de, ki Eleko wa ninu kẹkẹ ọla rẹ, pẹlu awọn wundia ti ọmu wọn duro l'aiya wọn bi "*A1*" 1, pẹlu Ligidigba to jire ni ibara idi wọn, pẹlu ilẹkẹ sẹgi ati ẹyinla ni ọwọ ati ọrun wọn, tiro tẹrẹ l'oju wọn, osun tẹrẹ nigbase, aşọ oke to dara lara wọn ninu kẹkẹ niwaju Eleko, bi a ba si ti kọ orin *God save the King*, ki Ọlorun gba ọba la tan, ki a bẹrẹ si kọ. Ẹru ọba ni mo ba, Eleko. Eleko afinju ọba, afinju oba te nf'ọla re ra, Eleko nbọ l'ọna, ọmọ——lo m a l'ọba ko si.

Bawo niba ti dun to. Alukọngi a fi ọrọ na kọ Gomina l'ọrun.

*GOD SAVE THE KING.*

Emi ni ti nyin nitoto,
ATARI AJANAKU.

---

[*Copyright*]

## "EKO AKETE" LAW REPORT.

[ Lati ọwọ ATOLUGBOKUN. ]

Suit No. 538/25.

J. B. FADIPE
*versus*
A. B. BAILEY
CECILIA SIFFRE

Lọya Adekunle Wright lo wa fun J. B. Fadipẹ. Akọwe Kotu wipe nwọn fun awọn mejeji ti wọn pe lẹjọ niwe şugbọn won ko wa. Fadipe bọ sinu apoti o bura. Alagbẹdẹ ni on, on şişẹ fun ologbe Bamkọle Bailey on si fi iwe iye owo ti on ma gba ranşẹ si ni gba aiye rẹ. Lẹhin na on kọ iwe si awọn Baba nsiku ati Iya nsiku ti a pe lẹjọ wọn yi. *Motor* ti on fun şe yi Idioro lo gbẹ ba jẹ ti on si tunşe n bẹ. Adajọ fun ni idajọ fun pọun marun şile mẹjọ to pe ẹjọ fun ati şile mejila owo irinşẹ.

Suit No. 545/25.

HANNAH ANNAN
*versus*
WILLIAM HAMILTON BINEY

Lọya Kayọde to wa fun ẹniti o pe ẹjọ wipe Biney jẹ on ni pọun mẹdọgbọn.

Lọya Ọlayimika Alakija lo wa fun Ọgbẹni Biney nigbati wọn pe ẹjọ yi nitori ko si ogbufọ to ma gbufo ni ede Fanti, ẹjọ yi ni lati yẹ titi di ọgbọn oşu *April* 1925.

Suit No. 410/25.

AIYELESO ỌLAKINDE
*versus*
AGENT B. ANDERSON & COY

Loya Adekunle Wright lọ wa fun ẹniti o pe ẹjọ nigbati wọn pe ẹjọ yi. Adajọ ko ri Oyinbo ti wọn pe lẹjọ, o ni ki Akowe pe Oyinbo yi nigba meta şugbọn a ko gbọ jẹ rẹ. Nigbana ni Lọya Wright wa pe ẹlẹjọ rẹ ko bọ sinu apoti ko bura. Aiyeleso Ọderinde bura, o ni on nton Baisikulu şe on nghe ita 22, Williams ni Eko Oyinbo Anderson pe on fun işẹ lati to awọn Baisikulu tuntun to de fun won on si fẹ gba owo işẹ on pọun kan şile mejila pẹlu abọ, on si şe iwe owo on ranşẹ on koi ti ri owo na gba lọwọ won di oni. Adajọ ni on fun ni idajọ fun pọun kan şile mejila pẹlu abọ lẹhin na ni Lọya Adekunle Wright ni owo irin ẹşẹ ti on kọ. Adajọ ni ki Oyinbo san şile mẹfa owo ipẹjọ ati pọun kan şile kan owo irin ẹşẹ Lọya.

ATOLUGBOKUN.

# LEVER STORES

FOR

# SOUVENIRS

OF THE

# PRINCE OF WALES

VISIT.

**POPULAR PRICES**

## 3d. 6d. 9d. & 1s.

## White's Golden Female Tonic.

A splendid Remedy for female diseases such as :—Barrenness, Weakness, Painful and Irregular Menstruation, Leucorrhœa (White's), Cramps Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A tendency to Miscarriage etc., etc.

*Price 10/- per Bottle.*

**Made and sold only by** VICTOR WHITE, Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B. Not obtainable elsewhere.*



### N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.
### OYINBO ***J. F. SICK***

Ọba Ilękę, Ile Ilękę, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilękę, orişirisi Ilękę wọnyi wa ni tita :—

Ilękę Oyinbo, Ilękę Rubber, Ilękę Olomi Waji, Ilękę Onikękọ, Ilękę Eiejo, Ilękę Ayinrin, Ilękę Oniwõrò ati Fadaka, Ilękę Kerewu, Ilękę Jòjò, Ilękę Òlokuta, Ilękę Oloruka, Ilękę Ẹlẹranko, Ilękę Didan Yinrinyinrin, Ilękę Meremere, Ilękę Mọjọkun, Ilękę Adumãdan.

Ẹ wa wo Ile ọja wa ; A ni nkan wọnyi fun tita :—

Ikoko Taba Onigi, Jigi, Aşọ Aran, Ẹrọ Agbado, Ife, Ọti Eleworo (*Beer*) ati Eleso Ajàrà (*Wine*), Awọn Onjẹ Ipanu, Aşọ Iş'ọşọ, Ẹrọ Ere Ọmọde, Ohun Ọşọ, Abẹlà (*Candles*) ati ẹgbagbeje ọja miran.

A nta Maşini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati Irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi òwò wa wa ni Rotterdam. a si ni Ile Owo ni :— Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).


### Thanks for Sympathy.

The undersigned begs to return sincere thanks to all kind friends who have by personal calls, letters or otherwise tendered their heart felt sympathy to him during recent bereavement in Feb. 28th last, occasioned by the loss of his dear wife Madam Beatrice Samuel at Abeokuta. His earnest prayer for one and all, is that God may not grant his repaying them similarly.

James Trebonius Samuel.

### ŞABU J. A. SULE—OLOGBE

A fẹ ki awọn ọrẹ ati onibara Ologbe J. A. Sule ti Eko ati ni Idalẹ mọ wipe a şi Şabu rẹ fun ọja tita, a si din owo ọja na si pọ ọ.

Irin işẹ kafinta, ti alagbẹdẹ a'i nkan bi agadangodo, apoti, posi ati ohun ọşọ oniruru ohun ti a'kọ le daruko tan: ya-wa wo tirẹ ki wọn to ra tan ma jẹ ki ọbọlẹ ki ọ.

## J. C. VAUGHAN

Ile-Ọja "Sheffield" ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "...ndsor" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun ...le fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

...ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun ...titi di oni.

...TARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu ...onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

---

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikan-...a, iṣe lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ...ti apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ...-Ọkan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa ...okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Şọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Ọwu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

Onta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati ...iṣe Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ

---

### Coffins to suit your Taste.

Coffins with Pillows, Shroud, Brass ...ges, and Removable Lids, on sale at ...Kessler's Establishment, 7, Labinjo ...ne, Lagos: also Gramophone Records, ...slamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

---

### Coffin ! Coffin !! Coffin !!!

With excellent workmanship and finish ...sale at Paul I. Samuel's Workshop ..., Campbell Street, Lagos.

Residence and Office 72 Igboşere Road Lagos.

---

### Ask From Kaduna Stores.

Everything for Bicycles, Motors, and Gramophones. Newly arrived Gramophones and Zonophones, at cheapest prices as follows :—

£1. 10s. od , £1. 15s. od. to £2. o. o.

We also stock special Louder Gramophone needles ; these needles play four-records at one time.

Yoruba and English records of the latest amusing time.

For Particulars apply to the Manager,

S. A. CLAY

No. 79, Ọdunfa Street, or
1, Macaulay Street,
Lagos.

---

Cable Address:—
"Steinafrik" HAMBURG

### E. H. STEIN & Co.

HAMBURG, Neuwall 16/18
Hildebrandhaus.
*AFRICAN MERCHANTS*

**ALL INDENTS EXECUTED.**

for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.
*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos :—

**Mr. Karimu Kotun**
3, DOSUNMU STREET.

---

### Ruby Plates ! Ruby Plates !! Ruby Plates !!!

BOON TO GOLDSMITHS

*Just arrived.*

Call at once and make your choice from —

DURO THOMAS,
55, Massey Street, Lagos.

# A. Kessler,

**7, Labinjo Lane,**

**Williams Street,**

***P.O. Box 459***

Highly Recommended :

CRYSTALL
LÖWENBRAUEREI HAMBURG
LAGERBIER

THE

# Pilsener Beer

*"Crystall" Brand*

*Light & Sparkling*

**Per Case**

**33s.**

**Send for a trial case to-day and convince yourself of the first quality of this Beer.**



## GBOGBONIṢE FUN OBINRIN

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, iju, E Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ ati orişirişi arun ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE

"SHAKE THE BOTTLE."

A nta Egbogi yi ni Ṣabu Egbogi Ọgbẹni Vic White, 41, Offin Road, Lagos.



## WO'BI ẸNIKEJI,

Oniruru Posi ti o wa fun tita ; lọdọ Pa I. Samuel owo wọn bẹrẹ lati Pọun me abọ titi de Pọun mejila şile mejila. E ri wọn ra ni 40, Campbell Street, Ile-isin Ṣọşi Ebenezer ; ati ni No. 7 Igboşere Road, nitosi *King's College*.



## White's Convulsion-Killer.

(FOR BOTH CHILDREN AND ADULTS

**Sold only by VICTOR WHITE, Esq.**

**The Reliable Dispensary.**

**41, Offin Road, Lagos**

DIRECTIONS :—For adults one Tablespoonful every halfhour until the fit is gone. As a preventive, one Tablespoonful every morning before food. For Children, one desertspoonful, in the same manner.

"SHAKE THE BOTTLE."



## EGBOGI AIPERI

(Fun Ọmọde ati Agbalagba.)

Akajuwe :—Fun Agbalagba, Şibi ti a fi njẹ iṣu meji-meji ni ababọ Wakati, titi aiperi na yio fi oluwa rẹ silẹ. Fun ọmọde şibi kọkan bakanna.

Ki Aiperi ma ba şeni :—Fun Agbalagba, ki a ma fi şibi meji-meji tẹlẹ inu lọrọ. Fun ọmọde şibi kọkan. Ki a mi igo na daradara ki a to mu egbogi na.

PRICE FIVE SHILLINGS (5S) PER BOTTLE


When replying advertisers please mention *"Eko Akete."*

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 21, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.